# Àbùdá Ìmédélò nínú Ìpèdè Apanilẹ́rìn-ín lórí Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé

**Saka, Idayat Oyèníkẹ̀ẹ́**
*Adeyemi College of Education,*
*Ondo, Ondo State, Nigeria.*
oyenikeidayat@yahoo.co.uk

**Àsamọ̀**
Ẹ̀rín jẹ́ ọ̀na kan pàtàkí tí ẹ̀dá máa ń gbà fi ìmọ̀sílára hàn lóri ìṣe tàbí ìpèdè ajẹmáwàdà. Onírúurú àwọn onímọ̀ ló ti sisẹ́ lórí ìpèdè apanilẹ́rìn- ín, ní pàtàkí jù lọ nínú àwọn ìwé lítírésọ̀ Yorùbá. Lára wọn lati rí Adejumọ̀ (2008), Àlàbá (2008), Àrẹ̀mú (2005), Fakẹ́yẹ (2016), Ọlatẹ́jú (2008) àti Ìsọ̀lá (2008) àti Raji (2010). Púpọ̀ nínú àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí ló dá lórí àkójọpọ̀ orísun ìpèdè apanilẹ́rín –ín, ọ̀nà ìfini- ṣẹ̀fẹ̀, àǹfàání àti ìwúlò àwàdà, èfẹ̀ síṣe àti àpárá dídá bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ láwùjọ àmọ̀ tí ọwọ́jà ìwádìí kò tí tàn dé ìrúfẹ́ ìpèdè apanilẹ́rín- ín tí a máa ń kà lórí ìtàkùn-àgbáyé. Látàrí èyí, iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àgbéyẹ̀wò àti ìtúpalẹ̀ ipa tí àwọn àbúdà ìmédèlò (pragmatic features) kó nínú ìtúmọ̀ ìpèdè apanlẹ́rìn-ín ti orí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé. Orí tíọ́rí àìbárámu (incongruity theory) ni a gbé ìtúpalẹ̀ àkójọ èdè fáyẹwò èyí tí a ṣàkójọ láti orí ẹrọ ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé 'whatapp, facebook àti twitter' kà. Ìwádìí fihàn pé orí ìfòròdárà onípọ́nna ní púpọ̀ àwọn ìsọ àpanilẹ́rín-ín lórí ẹrọ ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé máa ń tẹ̀ kí wọn tó lè jiṣẹ́ tí òlùsọ̀rọ̀ rán wọ́n. À-mọ-ọn- mọ̀- ṣẹ̀dá yàtọ̀ sí èyí tí a kò fẹ́ kí ó ṣẹlẹ̀, ní ìbámu pẹ̀lú àwọn àbùdá ìmédèlò nínú ìbánisọ̀rọ̀ ojoojumọ ni pupọ wọn máa ń jẹ́. Tó bẹ̀ẹ̀, ti wọ́n fi yàtọ̀ sí àwọn tí a lè yàgò fún nígbà tí a bá ń ṣàgbékalẹ̀ ìsọ tí kò mú ẹ̀rín dání. Ní ìbámu pẹ̀lú àkóónú ìmọ̀ ìmédèlò, iṣẹ́ fidí rẹ múlẹ̀ pé lórí èrò mọ̀-ọ́n nú, ìṣekókó-èrò, àti íyapa sí òsùnwọ̀n alájọṣepọ̀ ti 'Grice' ní àwọn adẹ́rínpòsónú máa gbé ìfọ̀rọ̀dárà onípọ́n-ọ́n-na to jẹ́ atọkùn ìṣẹ́ wọn kà.
***Ọ̀rọ̀ atọ́nisọ́nà:*** *Ìpèdè apanilẹ́rín-ín, Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé, Àìbáramu-ìtumọ̀, Òsùnwọ̀n alájọṣepọ̀*

**Abstract**
Laughter is an emotional process by which people react towards humourous texts. Extant studies on humour such as Adejumọ̀ (2008), Àlàbá (2008), Àrẹ̀mú (2005), Fakẹ́yẹ (2016), Ọlatẹ́jú (2008) àti Ìsọ̀lá (2008) àti Raji (2010) have focused on literary analysis especially on the etymology, taxonomy, approach, and their social impact as a means of communication in the society with little attention paid to the pragmatic analysis of humourous texts on social media. This study is therefore, designed to investigate the impact of pragmatic features in humourous texts on Social media with a view to determining their adherence or otherwise towards the contextual interpretation of the humourous text. The incongruity theory of humour served as the framework. Eight humourous texts were purposively selected from Whatsapp and Facebook. The finding revealed that majority of humourous texts on social media is constructed through punning which contextual necessitates ambiguity. In relation to pragmatic features, syntax of these texts is often and thoughtful structured in contrast with syntax of day-to-day-speeches. This established lexis in humour as being different from those which speakers could flout in non-humourous text. In accordance with the tenet of pragmatics, the study identified presupposition, relevance principle and Grice's conversational maxims as the pragmatic features through which the speaker cleverly presents the punning and incongruity ideas through which his intended meaning's implicature provokes laughter.
***Keywords***: *Humour, Social media, Incongruity, Conversational maxims*

## Ìfáàrà

Ìló ẹ̀rọ̀ àyélújára jẹ́ ọ̀nà kan tí àwọn ènìyàn ń gbà bá ara wọn sọ̀rọ̀ lódé òní. Àǹfààní àti ipa tó jọ jú ẹ̀rín ń kó nínú ìlera ẹ̀dá ló sọ ìsọ apanilẹ́rìn-ín di ọ̀nà ibánisọ̀rò pàtàkì láàgbáyé. Àmúlò yìí sí máa ń rọrùn nípa lílo àwọn òpó ìbánisọ̀rọ̀ lórí afẹ́fẹ́ bí i *'Whatsapp,*

*'Facebook', 'Linkdln', 'Chat on'*; àpàpọ̀ àwọn òpó yìí ló sarajọ pọ̀ dí ohun ti a pé ni ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé nínú iṣẹ́ yìí.

Tí a bá ní ká wo bí ìwádìí ti ṣàfihàn ìwúlò àti àǹfààní ẹ̀rín rínrín àti àwàdà ṣíṣe lórí ìwòsàn ẹ̀mí àti ara ẹ̀dá, kò sí bí ìgbà ti lè máa yí tó tí ìpèdè apanilẹ́rìn-ín yóò fi kúrò láwùjọ ọmọ ènìyàn. A ó ri pé, tí a bá fẹ́ máa gbé ìrònú tì, kò yẹ kí á nímọ̀ nìkan lórí ète àtipanilẹ́rìn-ín, ó yẹ kí á tún lè gbìyànjú àtiṣàlàyé ìpèdè apanilẹ́rìn-ín, bí ọ̀kan gbòógì nínú ọ̀nà ìtúraká tó fi ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ṣatẹ́gùn. Níwọ̀n ìgbà tí èyí ti lọ́mọ́ ètò ìbára-ẹni sọ̀rọ̀, a gbàgbọ́ pé ó ṣe é ṣe láti lè ṣàtúpalẹ̀ tàbí wá ìtumọ̀ fún ìpèdè apanilẹ́rìn-ín ní ìbámu pẹ̀lú ìmọ̀ àti òṣùwọ̀n òye ìmédèlò 'pragmatic view'.

Ìpèdè apanilẹ́rìn- ín jẹ́ àgbékalẹ̀ ìsọ níbi tí a ti fẹ ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ lójú ju bí ó ti yẹ lọ fó fi jẹ́ pé a lè tọ́ka sí ìtumọ̀ méjì tàbí mẹ́ta tí ìsọ náà ní nígbíyànjú àtí èrò àtígbé ẹ̀fẹ̀ kalẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí Jensen (2009) ti ṣàlàyé, Freud (1990) gbà pé ẹ̀yà ìpèdè apanilẹ́rìn-ín méjì ni a lè gbé kalẹ̀ nínú ìbánisọ̀rọ̀. Àwọn náà ni: ọ̀rọ̀ àti èrò apanilẹ́rìn-ín. Onímọ̀ yìí tẹ̀síwájú láti ṣàpèjúwe ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn. Ẹ gbọ́ bí ó ti wí:

> Verbal humour occurs when an aspect of language, such as structural ambiguity, is exploited in order to achieve a humorous effect while the conceptual humor involves concept or idea that are thought of as humorous without using aspects of language for other purposes conveying the humorous message.
>
> ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn-in máa ń wáyé nígbà tí olùsọ̀rọ̀ bá ń ṣàmúlò wúnrẹ̀ kan tàbí méjì nínú apákàn àgbákalẹ̀ ìsọ rẹ̀ láti fi dá ẹ̀rín pànìyàn, nígbà tí èrò apanilẹ́rín máa ń wáyé níbi ó ti jẹ́ pé kókó èrò inú ìsọ olùsọ̀rọ̀ gan ní ó sokùnfà ẹ̀rín fún àwọn olùgbọ́ lái lo ẹyọ ọ̀rọ̀ kan soso.

Tí a bá tẹ̀lé àlàyé Freud bí ó ti hàn lókè yìí, orísìí ẹ̀yà ìpèdè apanilẹ́rìn-in méjì gbòòrò náà ní a lè yà sọ́tọ̀. Àwọn náà ni ọ̀rọ̀ apanilẹ́rìn- ín àti èrò apanilẹ́rìn-ín. O jẹ́ kí ó dí mímọ̀ pé ohun tó pa ẹnikan lẹ́rín-ín lè má nítumọ̀ ẹ̀ẹ̀rín létí ẹlòmíràn rárá. Èró yìí gan-an ni Jensen (2009:2) fúnrarẹ̀ni ṣàwàgúnlè nínú ìwòye rẹ̀ tó fi jẹ́ kí a mọ̀ pé ọ̀gàngan àyè, àsìkò àtí ọ̀nà tí a ti gbé ìsọ àwàdà kàlẹ̀ máa ní í ṣe lórí bóyá ìsọ mú ẹ̀fẹ̀ dání tàbí rárá.

Wàyí ò, tí a bá ní kí wo ọ̀nà ìmẹ́fẹ̀ṣe lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé, àwòràn ojú, etí àtí inú ló se agbátẹ̀rù ìmọ̀sílára ẹ̀fẹ̀ àti ẹ̀rín tí a rí dìmú nínú ìpeddè apanilẹ́rìn-ín. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, àgbékalẹ̀ àwàdà lórí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé máa ń dá lórí àlòpọ̀ àwóràn alálàyé àti ọ̀rọ̀ ẹnu, nínú wọn a rí èyí tó gùn ti a gbé kalẹ̀ bí ìtan- sọ-kí-ń-sọ láàárin ènìyàn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, bẹ́ẹ̀ sì ní àwọn tó dá lórí ọ̀rọ̀ àdásọ náà kò gbẹ́yìn. Ìlànà lílo fọ́tò aláwòrán lásán àti fọ́tò alọ́rọ̀-nínú lórí '*fesibúùkù tàbí wàsáàbù'* máa ń tètè jẹ́ kí òté ẹ̀rín ínú àwàdà fojú hànde tó bẹ́ẹ̀ ti èróngbà adẹ́rìn-pòsónú tó gbé ìsọ apanilẹ́rìn-ín kalẹ̀ yóò fi wá sí ìmúṣẹ. Ìṣe-nǹkan-lárọ̀ọ̀tọ̀ èyí tó mú olùsọ̀rọ̀ ri ara rẹ̀ bi ọ̀gá lórí àwọn to lòdí sí ọ̀nà ìgbàṣe-nǹkan tirẹ̀ jẹ́ ọgbọ́n tàbi ète pàtàkì kan ti àwọn adẹ́rín-ín-pòsónú lórí sósíó midià máa ń lò Saka (2017: 214-232).

Tí a bá wá ń sọ̀rọ̀ nípa ẹ̀fẹ̀ tàbí àwàdà síṣe, a kò lè fọwọ́ rọ́ ìfọ̀rọ̀dárà ṣẹ́yìn rárá. Ìfọ̀rọ̀dárà ní a rí bi àmúlò gbólóhùn tàba ìsọ lọnà tó fi ni ìtumọ̀ púpọ̀ létí olùgbọ́. A tún lè kì í bí ìlò ọ̀rọ̀ alójú- lódì níbi tí gbólóhùn méjì tó ní ọ̀rọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ àmọ́ tí ó jẹ́ pé bákan náà ni ìhun síńtáàsì wọn rí nípa pé, ọ̀kan-ùn ni ìró wọn. Ẹ̀wẹ̀, irú ìfọ̀rọ̀dárà tí ìṣẹ́ yìí dálé ń tọ́kasí àwọn èyí tí ó ń ṣàfihàn ìtúmọ̀ méjì tàbí mẹ́ta látàrí ìlò ọ̀rọ̀ tí ó jọra níròó tàbí nìhun fún ète àtipanílẹ́rín-ín lágbo àwàdà. Ìṣàmúlò ìfọ̀rọ̀dárà nírú àyè ìgbẹ́fẹ̀-kalẹ̀ ló sọ àgbékalẹ̀

gbólóhùn apanilẹ́rín-ín di ọ̀tun tàbí di ohun titun létí olùgbọ́ tó bẹ́ẹ̀ tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn máa fi jásí ìfìnìṣẹ̀fẹ̀.

**Tíọ́rì Àmúlò**

Isẹ́ yìí ṣe àmúlò tíọ́rí aìbáramu 'incongruity theory' èyí tó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn tíọ́rì tó dá lórí ìpèdè apanilẹ́rìn- ín. Ìgbàgbọ́ àwọn agbátẹ́rù tíọ́rì yìí ni pé ẹ̀rín a máa jẹ jáde láti ara èdè-àìyedè lááàrin nǹkan tí à ń retí àti nǹkan tó sẹlẹ̀ gan- an níńu ìsọ apanilẹ́rìn-ín. Kí a tilẹ̀ sọ pé, àlàkalẹ̀ tíọ́rì àìbáramu gbà pé àwọn ènìyàn máa ń rín ẹ̀rín sí nǹkan ìyanu to yapa tàbí yàtọ̀ sí ohun àjọgbà àwujọ̀, àwọn ohun báyìí a máa súnmọ́ àwọn ìṣe àgbọ́-ṣe- hàáà, èyí tí kò mú wàhálà dání sùgbọ́n tí ó yàtọ̀ tàbí lòdi sí ìṣe tó gbajú gbajà. Èrò yìí ni Wilkings (2009:352) yàn-nà ná nígbà tó ní:

> The incongruity theory purports that people laugh at things that surprise them or at things that violate an accepted pattern – with a difference close enough to the norm to be nonthreatening, but diffrenc enough from the norm to be remarkable.
>
> Tíọ́rì àìbárámu- ìtùmọ gbà pé àwọn ènìyàn a máa rẹ́rìn-ín sí ohun tó yàwọ́n lẹ́nu tàbí ohun to yapa si àjọmọ̀ àwùjọ- tó súnmọ́ ìṣesí aláìṣéégbà àmọ́ tó yàtọ̀ gédégédé sí ìṣesí to jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà.

Irin iṣẹ́ yìí tẹpẹlẹ mọ́ ìwúlò ọgbọ́ń inú lati lè ṣe àwárí ohun tó bójúmu níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé, ọgbọ́n inú lo lè mú ẹ̀dá kíyèsí ìyàtọ̀ tó bá ìrírí wọ́n mu ní àwọn àyè kan yàtọ̀ sí òmíràn. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, ìtumọ̀ ajárètí èyí tó jẹyọ látàrí àìbárámu èrò inú àwàdà máa ń ṣàfihàn ìyàlẹ́nu, tó fi wá jẹ pé ìtumọ̀ àrà –ọ̀tọ̀ ni a saábà máa ń ri dìmú. Ìtumọ̀ yìí gan- an ni ó fún olùsọ̀rọ̀ ní àǹfààní láti gbé ọ̀kan àwọn olùgbọ́ kúrò lórí ìtumọ̀ ìpìlẹ̀ lọ sí èrò tàbí ìtumọ̀ tó yàtọ̀ gédégédé. Ní ìbámu pẹ̀lú àkóónú tíọ́rì yìí, kì í ṣe àwígbọnnú tí a bá ní àmì ìyàlẹ́nu gan-an ni o jẹ́ agbátẹ́rù tàbí okùnfà ẹ̀rín tí ó máá súyọ nínú ìpèdè àwàdà. Kókó mẹ́ta tí a ri fàyọ bí àbùdá àkóónú tíọ́rì àìbaramu nìwọ̀nyí:

i. Ìtumọ̀ àwàdà máa ń dá lórí aìbaramu ìtumọ̀ lááárín ohun ti à ń retí àti èyí tí a kò níran rẹ̀.
ii. Orí ọ̀rọ̀ onípọ́nna ni ìjẹyọ àìbaramu ìtumọ̀ ti máa ń jẹ jáde nínú ẹ̀hun ìsọ àwàdà.
iii. Ìyanilẹ́nu ni okùnfà ẹ̀rín tó jẹyọ nínú ìsọ àwàdà, ẹ̀fẹ̀ tàbi fàbú àtipé,
iv. Ìtúraká ní ó máa ń jẹ́ àbọ̀silẹ̀ àìbáramu ìtumọ̀ tó fa ẹ̀rín nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìsọ apanilẹ́rín-ín.

**Ìmọ̀ Ìmédèlò àti Ìpèdè Apanilẹ́rìn-ín**

Ìmọ̀ ìmédèlò ló dá lórí bí a ṣe ṣàmúlò èdè ní ìbámu pẹ̀lú ìtumọ̀ ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ pàtàkì. Onírúurú àbùdá ìmédèlò ni ó máa ń jẹyọ nínú ìsọ apanilẹ́rìn-ín, lára àwọn àbùdá wọ̀nyí lati rí: èrò mọ̀-ọ́n-nú (presupposition), ìlànà alájọṣepọ̀ lááàrin òlùsọ̀rọ̀ (Cooperative maxims) àti Òsùnwọ̀n ìṣekókó (Principle of Relevance).

**Èrò Mọ̀-ọ́n- nú**

Èrò mọ̀-ọ́n- nú jẹ́ òye tàbí ìmọ̀ tí olùsọ àti olùgbọ́ ti dìjọ ní lórí ìba ìṣẹ̀lẹ̀ kan ṣíwájú kí ìṣẹ̀lẹ̀ tí à ń sọ náà tó ṣẹ̀. Èrò yìí ló ń tọ́ka sí kókó inú ìṣẹ̀lẹ̀ kan tó ti ṣẹ̀ ṣáájú èyí tó ń lọ lọ́wọ́lọ́wọ́ tó fi jẹ́ pé, ìṣẹ̀lẹ̀ àṣẹ̀ṣẹ̀ṣẹ̀ yìí fara pẹ́ tàbí ní ṣe pẹ̀lú èyí tó kọjá rẹ̀. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé, okùn ọrùn ìṣẹ̀lẹ̀ tẹ̀lẹ̀ rọ̀mọ́ èyí tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń ṣẹlẹ̀. Òye yìí ni a ní lérò pé olùsọ̀rọ̀ ní lórí bóyá olùgbọ́ yóò gbà tàbí lòdì sí ọ̀rọ̀ tí òun gbé kalẹ̀. Ó jẹ́ ìtumọ̀ àjọgbà tàbí àjọmọ̀ lááárín lùsọ̀rọ̀ àti olùgbọ́ lórí èrò tó jẹyọ ṣáájú ìtàkurọ̀sọ. Ohun tí a fi sọ èyí ni pé, tí kò bá sí àjọgbà èrò

kankan tẹ́lẹ̀ lórí àkòrí tí àwọn akópa nínú ìbánisọ̀rọ̀ yàn-nà-ná, ìbánisọ̀rọ̀ kò ní lọ gere, èyí tí ó sì lè pagi dínà èrò alájọṣepọ̀ tó máa ń wáyé láàárín olùkópa nínú ìbánisọ̀rọ̀. Bí àpẹẹrẹ, ẹ jẹ́ kí á wo ìtàkurọ̀sọ tó wáyé láàárín oníṣègùn òyìnbó àti aláìsàn nínú ilé ìwòsàn yìí:

(1) **Doctor:** You look so tired and exhausted, are you taking three meals per day like I advised.
**Patient:** It must be your handwriting. I thought you wrote three males per day. You wrote three males per day.

**Oníṣègùn:** Ẹ máa rù u, ǹjẹ ẹ̀ ń jẹun ẹ̀mẹ̀ẹ̀ta ojúmọ́ bí mo ti sọ bí?
**Aláìsàn:** Ọwọ́ ìṣọwọ́-kọ̀wé yín ló máa jẹ́ ó, mo lérò pé ọkùnrin mẹ́ta ojúmọ́ lẹ kọ ni Ọkùtrin mẹ́ta ojúmọ́ lẹ kọ.

Èrò mọ̀-ọ́n-nú méjèèjì dá lórí pé óunjẹ tó dára ló ń ṣatọ́kùn ìlera pípé, àtipé ó kére tán ẹni tí kò fẹ́ kí àìsàn kọ lu òun gbọdọ̀ lé máa jẹun ẹ̀mẹ̀ẹ̀ta lójúmọ́. Èró yìí ló fi pọn dandan fún aláìsàn tó sẹ̀sẹ̀ ń bọ̀ sípò látí mú ounjẹ ẹ̀mẹ̀ẹ̀tà lọ́kùnńkúndùn àmọ́ dípò ounjẹ, ìfẹ́kúfẹ́ ara nípa níní ìbáṣepọ̀ pèlú ọkùnrín lẹ́mẹ̀ẹ̀ta lójúmọ́ ni aláìsàn gbájúmọ́. Láísí-àní- àní, ìwà nàbi yíí gan ló fa àìsàn èyí tó mú aláìsàn rù kú eegun yàtọ̀ si tàirí- óuńjẹ jẹ. Isẹ́ tí ìfọ̀rọ̀dárà onípọ́nna *'meals àti males'* ń ṣe níbí ni láti ṣafìhàn ìsẹ̀lẹ̀ mọ̀- ọ́n nú tó fá ìsẹ̀lẹ̀ tó ń lọ lọ́wọ́lọ́wọ́.

## Ìlànà Ìṣekókó

Òsùnwọ̀n ìṣekókó-èrò nínú ìmọ̀ ìmèdèlò gbà pé ohun tí ó yẹ ní mímójútó nígbà tí a bá rán èdè nísẹ́ ni láti fi èdè ṣàgbékalẹ̀ ohun tí ó ṣe kókó nínú ìsọ. Ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà yìí, olùsọ̀rọ̀ máa gbìyànjú láti gbé ìsọ tí ìtumọ̀ rẹ̀ kò farasin kalẹ̀ pẹ̀lú àmúlò àgbékalẹ̀ gbólóhùn tó lọ geere. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, ó ṣe é ṣe kí irú gbólóhùn báyìí ní ìtumọ̀ tó yàtọ̀ ní ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn, ẹ máa jẹ́ kí á gbàgbé pé ìtumọ̀ kan tó ṣe kókó tó sì ní í ṣe pẹ̀lú ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ ni olùsọ̀rọ̀ ní lọ́kàn. Pàtàkì òsùnwọ̀n ìṣekókó nínú ìtàkurọ̀sọ ló máa ń ran olùgbọ́ lọ́wọ́ láti lè di ìtumọ̀ tó ṣe kókó mú tí yóò sì fojú fo àwọn ìtumọ̀ mìíràn tí ìsọ olùsọ̀rọ̀ lè ní. Àwọn agbátẹrù ìlànà ìmèdèlò yìí gbà pé tí a bá ṣàtúpalẹ̀ bí èrò ti ṣe kókó sí láàrin ìsọ àti àyè tí ó ti jáde, ó didan kí a rí èyí kókó gan tí olùsọ̀rọ̀ ní lọ́kàn yàtọ̀ sí àwọn ìtumọ̀ mìíràn (Sperber &Wilson, 1995). Àmọ́, ó ṣe é ṣe nígbà mìíràn kí ìyapa wáyé nígbà tí olùgbọ́ bá finúfíndọ̀ túmọ̀ ìsọ olùsọ̀rọ̀ sódi lọ́nà àti fi èrò ajárètí hàn sí èrò ohun àṣìlò. Ẹ jẹ́ kí a wo bí ìsọ̀ apanilẹ́rín- ín ìsàlẹ̀ yìí tí ṣàwàgúnlẹ̀ àlàyé ti a se lòke yìí sí:

(2) **Teacher:** How can we keep our school clean?
**Student:** By staying at Home.

**Olùkọ́:** Báwo ni a ṣe lè mú kí àyìká ilé –ìwé wa mọ́?
**Akẹ́kọ̀ọ́:** Nípa kí a jókòó sílé.




Tí a bá wo àyọlò òkè yìí dáradára, a ri pé èsì àkẹ́kọ̀ọ́ yapa sí kókó-èrò ṣíṣètọ́jú àyíká tí olùkọ́ nírètí tí a bá gbà pé èrò- yíyan-ilé -ìwé -lódì nítumọ̀ mìíràn lọ́gangan ìṣẹ̀lẹ̀ ibi tí a ti nírètí ìlànà mímójútó nǹkan tó fẹ́ bàjẹ̀ látàrí ìwà ìdọ̀tí. Ìtumọ̀ yìí báramu lọ́gangan èrò ọmọ níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé, àyíká ilé-ìwé yóò wà ní mímọ́ nígbàkúgbà tí àwọn àkẹ́kọ̀ọ́ kò bá

sí ní ilé-ìwé àmọ́, ó járètí èrò olùkọ́ nípa pé èsì náà kò ṣe kókó tó nínú èrò olùkọ́. Ẹ tún gbọ́ bí àgbékalẹ̀ ìsàlẹ̀ yìí ṣe pani lẹ́rín- ín látàrí yíyapa ṣí ìṣe kókó èrò:

(3) **Child:** Mum, can you imagine that yẹ̀yẹ́ man. He said I should come to his house so he can see my pant.
**Mother:** What? And what did you do?
**Child:** I went to his house without my pant so he won't see it. (Simile at surface level but figurative at deep meaning)

**Ọmọ:** Ìyà mi, ẹ ò tilẹ̀ rí oníyẹ̀yẹ́ ọkùnrin yẹn. Ó ní kí ń wá sílé òun léte àtijẹ́ kí òun rí páńtí mi
**Ìyá:** Hẹ̀ín, kí ni ó wá ṣe?
**Ọmọ:** Mo lọ síbẹ̀ láìwọ páńtí torí kó má ba à rí i.

Orí ìfọ̀rọ̀dárà alárokò ní adẹ́rín-ín-pòsónú tẹ̀ làtí ṣàwàgúnlẹ̀ èròńgbà rẹ̀ nínú ìsọ òkè yìí. Ní ìhun òkè, òye ìfọ̀rọ̀dárà ni olùgbọ́ ní, àmọ́ ìtumọ̀ alárokò ni olùsọ̀rọ̀ múlò ní ìhun ìsàlẹ̀. Àyè ìṣẹ̀lẹ̀ tí olùsọ̀rọ̀ ń tọ́ka sí kò fi bẹ́ẹ̀ yé olùgbọ́ tó, èyí ló fa èsì tí ó fọ̀, inú èsì yìí sì ni àṣehàn ẹ̀rín ti jẹ jáde.

Ọmọ ṣe àfiwé fífi ojú rí nǹkan lásán nígbà tó jẹ́ pé rírí ibi kọ̀lọ́fín ìyẹn ìhòhò ẹni ni kókó èrò tí olùsọ̀rọ̀ ní lọ́kàn lọ́gangan àyè ìpèdè àpólà ìṣe, *see pant*, 'fojú rí pátá àwọ̀tẹ́lẹ̀'. Àmúlò àpólà ìṣe yìí gan jẹ́ atọ́kùn ìfọ̀rọ̀dárà onípọ́nna tí a gbọ́ nínú àgbékalẹ̀ náà, bẹ́ẹ̀ sì ní; òhun ló bí àṣìgbọ́ tàbi àìgbédè èyí tó ṣàtọ́kùn ìwà òmùgọ̀ tí ọ̀dọ́bìnrin náà hù. Orí ìtumọ̀ àìgbédè tí ọmọbìnrin dìmú ló dàbí òté tí ó gbé ẹ̀rín inú ìtàkurọ̀sọ̀ tó wàyé ni àpẹẹrẹ (3) dúró. Àìlóye lórí kókó èró inú ìsọ ló mú ọmọ ṣe àfiwé 'ífojúrí nǹkan lásán' nígbà tí ó jẹ́ pé 'ìhòhò-ẹni' ni kókó èrò tó bí àgbékalẹ̀ ọ̀rẹ́kùnrin rẹ̀.

## Ìfọ̀rọ̀dárà àti Ọ̀gangan Ìṣẹ̀lẹ̀

Ìfọ̀rọ̀dárà-onítumọ̀ pọ́n-ọ́n na máa ń lọ̀ọ̀rìn ju ọ̀rọ̀ geere lọ látàrí àǹfààní tí olùsọ̀rọ̀ ni sí onírúurú ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ èyí tí ìlò ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ tí a fẹ̀ lójú ti lè wáyé. Nígbà tí èyí sì ti rí bẹ́ẹ̀, a ó ri pé ó di dandan kí olùsọ̀rọ̀ yan àyè ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó bá ìsọ rẹ̀ mu. Ohun tí à ń sọ ni pé, yíyan ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó tó jẹ́ dandan torí pé, ó máa ní í ṣe lórí fífún ìfọ̀rọ̀dárà nítumọ̀. Àyè ìgbọ́rọ̀-kalẹ̀ tí a yàn ni yóò ṣatọ́kùn òté tí ó gbé ìtumọ̀ ìfọ̀rọ̀dárà dúró. Tí a kò bá gbàgbé nígbà tí à ń sọ̀rọ̀ lórí àlàkalẹ̀ ìlànà ìṣekókó, ìtumọ̀ tó ju ẹyọ kan lọ ló mọ̀-ọ́n-mọ̀ wáyé nínú àgbékalẹ̀ ìfọ̀rọ̀dárà, ṣùgbọ́n olùgbọ́ máa ń fojú kéré tàbí fò ìtumọ̀ àrọ́wọ̀tó láti wá ìtumọ̀ mìíràn tó tún lè jẹ́ aṣeégbà bí àlàyé èrò inú ìfọ̀rọ̀dárà.

Wàyí ò, kí ìfọ̀rọ̀dárà tó níyì, ó di ìgbà tí olùsọ̀rọ̀ bá tó lè fún un ní ìtumọ̀ tó ju ẹyọ kan lọ ní ìbámu pẹ̀lú ìṣekókó ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ tí a mọ̀-ọ́n-mọ̀ yàn láàyò. Ẹ jẹ́ ká yiri àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí wò:

(4) 'If all Guys are the same
Who told you to date them all.'

*'Tí gbogbo ọkùnrin bá jẹ́ ọ̀kan-ùn*
*Dandan ni kí ó bá wọn jáde ni?*

Ọ̀rọ̀ ti a fàlà sí nídìí nínú àyọlò òkè yìí 'date' jẹ́ àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀ onítumọ̀ púpọ̀ àmọ tí ìró wọn jẹ́ bákan náà. Èyí túmọ̀ sí pé *'date'* bí àmúlò ọ̀rọ̀ nínú ìsọ̀ òkè yìí mú pọ́nna dání. Àwọn ìtumọ̀ tí ó lè ni nìwọ̀nyí:

i. oǹkà-ọjọ́ nínú ọsẹ̀
ii. ọ̀rọ̀ ìṣe àyálò lédè òyìnbó fúu ìmọ́nṣe wọlé-wọ̀de pẹ̀lú ẹnìkan.

Wúnrẹ́n 'date' ni ó jẹ́ ọpákútẹ̀lẹ̀ fún ẹ̀rín tó súyọ nínú ìhun ìpèdè apanilẹ́rìn-ín ti (4) òkè yìí. Ẹ̀rín jẹyọ nínú ìtàkurọ̀sọ̀ yìí nítorí pé olùgbọ̀ fojú fo ìtumọ̀ àrọ́wọ́tó 'date' bí ọ̀ǹka-ọjọ́ tó wá yan ìtumọ̀ mìíràn lááyò ní ìbámu pẹ̀lú ìṣekóló ọgangan ìṣẹ̀lẹ̀ èyí tó ní í ṣe pẹ̀lú àmúlò ọ̀rọ̀ 'guys' àti 'girls'.

Àfayọ láti inú àlàyé òkè yìí fi yéwa pé a lè ka ìfọ̀rọ̀dárà sí ẹ̀yà ìpèdè apanilẹ́rìn-ín níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé ìhun ìtumọ̀ rẹ̀ máa ní í ṣe pẹ̀lú àfiwé tàbí àgbékalẹ̀ méjì tó jọra àmọ́ tí wọ́n yàtọ̀ ní kíkọ sílẹ̀. Òye ìlò ọ̀rọ̀ lọ́gangan ìṣẹ̀lẹ̀ yìí kan náà ló bí ẹ̀rín inú ìsọ (5) ìsàlẹ̀ yìí:

(5) Driver: My vehicle papers are in Order. So as a law abiding citizen, I'm not going to give you a kobo.
Policeman: With a sticker that says, I'm a cheerful giver on your car? You're under arrest for misleading the public.

Awakọ̀: Ìwé ọkọ̀ mi pe pérépéré. Níwọ̀n ìgbà tí mó si jẹ́ ẹni tó pòfin ìlú mọ́, n kò ní owó kankan.
Ọlọ́pàá: Ṣé pẹ̀lú àlẹ̀mọ́kọ̀ tó ń sọ pé 'mo jẹ́ olùfúnni tòótọ́ lára ọkọ̀ rẹ'? ọwọ́ òfin bà ọ́ fún sísi ara ìlú lọ́nà.

Ìtumọ̀ ti 'I'm a cheerful giver', *'mo jẹ́ olùfúnni tòótọ́'* ní létí ọlọ́pàá yàtọ̀ sí èyí tó ní létí awakọ̀. Àìbáramu ìtumọ̀ wáyé láàárín àwọn olùsọ̀rọ̀ nípa pé ìṣesí awakọ̀ yapa sí ìtumọ̀ gbígbòrò ti àkọmọ̀nà ára mọ́tò rẹ̀ ní. Ohun tó fa èyí kó jú pé awakò lòdí sí ìtumọ̀ tipa-tìkúùkù àti ìfinú-fẹ́dọ̀ tí ọlọ́pàá ra bọ àkọmọ̀nà ara ọkọ̀ lọ́rùn lọ́gangan ìṣẹ̀lẹ̀ ìjẹkújẹ àti ìwà olè tó ti gbèrú lọ́kan ọlọ́pàá. Àpẹẹrẹ mìíràn tún nìyí:

(6) Wife: If I had known you were this poor, I wouldn't have married you!
Husband: When I was telling you that you are the only thing I have in this world, what were you thinking?
Ìyàwó: Kání mó ti lóye pé báyìí ló tí tálákà sí ni, n kò bá má tí fẹ́ ọ!
Ọkọ: Nígbà tí mó ń pariwo fún ọ pé ìwọ nìkan ní mó ní láyé yìí, kí ni ò ń rò?

Ìfọ̀rọ̀dárà onípọ́n-ọ́n-na tó wáyé nínú ìsọ òkè yìí wáyé láàárín ìtumọ̀ eréfèé àti ìjìnlẹ̀ awẹ́ gbólóhùn 'the only thing I have in this world', *'ohun kan soso tí mo ní láyé yìí'*. Ìyàwó fara mọ́ ìtumọ̀ eréfèé, èyí tó dàbí síṣàpọ́nlé tàbí pípọ́n ènìyàn tó ń tọ́ka sí bí ọkọ ti nífẹ̀ẹ́ aya rẹ̀ sí sùgbọ́n tí èrò ọkọ ń tọ́ka sí òótọ́ ọ̀rọ̀ tó fi ipò àti àrọ́wọ́tó rẹ̀ sí dúkìá àti ọ̀rọ̀-ayé hàn. Gẹ́gẹ́ bí àrìdìmú, ohun pàtàkí tí ó fojú hànde nínú àpẹẹrẹ (4), (5) àti (6) òkè wọ̀nyẹn ni pé, tí a bá ní kí a fojú wó bi ìfọ̀rọ̀dárà ti máa ṣàfihàn ìtumọ̀ ajárètí tabí àìbáramu sí, a kúku tún lè rí bí ẹ̀yà pọ́n-ọ́n-na gan- an fúnrarẹ̀. Ìhun ọ̀rọ̀ bí ó ṣe jẹyọ lọ́gangan ìsẹ̀lẹ̀ ló sì máa ń fa ìfọ̀rọ̀dárà onípọ́n ọ́n-na tàbí kí odidi gbólóhùn tàbí apákan ìhun gbólóhùn ní ju ìtumọ̀ kan lọ.

**Ìlànà Alájọṣepọ̀ láàárín Òǹkópa nínú Ìbánisọ̀rọ̀**

Ìfọ̀rọ̀-sábẹ́ -ahọ́n-sọ jẹ́ ètè kan pàtàkì tí àwọn olùkópa nínú ìbánisọ̀rọ̀ máa ń lò léròǹgbà àtikógojá ninu òfin alajoṣepo tínú Ìbánisọ̀rọ̀. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Grice (1975), a ti máa ń gbà pé olùsọ̀rọ̀ àti olùgbọ̀ ti ní àjọṣepọ̀ kan ṣáájú lágbo ìbánisọ̀rọ̀, èyí ló fà á tí wọ́n fi lè dìjọ kojú síra láti sọ̀rọ̀ tàbí yiri èrò kan láàárín ara wọn; àtipé àjọṣepọ̀ tó ti wà tẹ́lẹ̀ yìí ló máa ṣatọ́kùn

ọ̀nà bí olùgbọ́ yóò ti fèsì. Àwọn àjọṣepọ̀ wọnyí ni Ọ̀jọ̀gbọ́n yìí parapọ̀ pè ní "ètò alájọṣepọ̀" (cooperative principle). Ètò alájọṣepọ̀ yìí dá lórí Ìlànà àti òte ìgbáfọ̀kalẹ̀ onílànà-mẹ́rin. Òsùnwọn kọ̀ọ̀kan ló fi ṣàmì àwọn ètò alájọṣepọ̀ ọ̀hún. Àwọn òsùnwọ̀n náà nìwọ̀nyí:

**(a) Òṣùwọ̀n iye:** Àlàkalẹ̀ òsùnwọ̀n yìí ní pé, èsì olùgbọ́ gbọ́dọ̀ wà ní déédé ìwọ̀n tàbí iye tí olùsọ̀rọ̀ nílò. Bẹ́ẹ̀ sì ni pé, ọ̀nà ìgbọ́rọ̀kalẹ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tó ṣàfihàn kókó pàtàkì inú ìsọ.

**(b) Òṣùwọ̀n òótọ́:** Ní ìbámu pẹ̀lú òsùnwọ̀n yìí, olùkópa ńnú ìbánisọ̀rọ̀ kò gbọdọ̀ parọ́ tàbí sọ ohun tí kò nímọ̀ kíkún nípa rẹ̀.

**(d) Òṣùwọ̀n ìṣekókó:** Ètó yìí gbà pé, ìsọ olùsọ̀rọ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tó wúlò fún kókó èrò inú afọ̀.

**(e) Òṣùwọ̀n ọ̀nà ìgbàṣeǹka**: Òfin yìí gbà pé olùkópa nínú ìbánisọ̀rọ̀ gbọdọ̀ ṣe nǹkan tààrà, kí ó sí yàgò fún ìlò pọ́n-ọ́n na àti àìpọ̀jù ọ̀rọ̀ kí ìtumọ̀ má ba à lọ́júpọ̀.

Ẹ jẹ́ kí á sàyẹ̀wò sí bí àwọn adẹ́rìn-ín pòsónú tí yapa sí àwọn òsùnwọn òkè wọ̀nyí nínú àgbékalẹ̀ ìpèdè apanilẹ́rìn-ín wọn lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọn-kálé:

## Ìyapa sí Òṣùwọ̀n Iye

Ẹ wo bí ọmọbìnrin yìí ṣe fọwọ́sí ìwé ìdánwò JAMB rẹ̀:

(7)
Name: Oken Ekaete Ndifinke
Age: 19
Sex: 3 times daily!!

Orúkọ: Oken Ekaete Ndifinke
Ọjọ́-orí: 19
Akọ/Abo: Ẹ̀mẹ̀ẹ̀ta ojúmọ́

Bí ó ti han nínú àpẹẹrẹ (7) òkè yìí, esì ọmọbìnrin tí lágbara jú ohun tí àwọn asẹbéèrè nílò lọ bẹ́ẹ̀ sì ni pé èrò tí èsì rẹ̀ fihàn yapa sí kókó pàtàkì ti ìbéèrè dálé ní abẹ́ ako-n- bábo. Ní sókí, àgbékalẹ̀ ọmọ yapa sí òṣùwọ̀n iye torí pé èsì rẹ̀ tí ju iye tí àwọn asẹbéèrè nílò lọ tó bẹ́ẹ̀ tó fi sọ kókó pàtàkì inú ìsọ nù.

## Ìyapa sí Òṣùwọ̀n Òótọ́

Èyí máa ń wáyé nígbà tí aṣafọ̀ bá gbé irọ́ kalẹ̀ bí òótọ́. Bí àpẹẹrẹ:

(8)
Man: Hi! I'm 32
I'm a politician and I'm honest
Lady: Hi! I'm 29
I'm a prostitute and I'm a virgin (contradiction)

Arákùnrin: Báwo ni! Mo jẹ́ ọmọ ọdún méjìlélọ́gbọ̀n.
Olóṣèlú àtí olóòótọ́ ènìyàn ni mí.
Arábìnrin: Báwo ni! Mo jẹ́ ọmọ ọdún mọ́kàndínlọ́gbọ̀n.
Asẹ́wó èyí tí kò tí ì ọmọkùnrin rí ni mí.

Tí a bá wó kókó èró ti àwọn olùsọ̀rọ̀ méjèèjì ń yiri wo, a ó ri pé orí èrò mọ̀n-ọ́n-nu pé ìrọ́ pípa ló máa ń mọ́rọ̀ dùn ni àwọn olùsọ̀rọ̀ òkè yìí gbé ìtàkurọ̀sọ wọn kà. kété tí

ọmọbinrin gbọ bí arakunrin ti júwe ara rẹ̀ tán ni òun náà bá fi àwòràn inú pẹ̀lú òye mọ̀n-ọ́n-nú lórí irú ẹ̀dá tí àwọn olóṣèlú jẹ́ gbé àpèjúwe tirẹ̀ náà kalẹ̀. Ìtumọ̀ àlàyè tí a ṣetán yìí ni pé, Orí èrò rírí àwọn olóṣèlú bí àpuró- jẹun ni ọmọ náà gbé èsì àti àpèjúwe rẹ̀ kà. Tí kò bá rí bẹ́ẹ̀, báwó ní ẹni to pé ara rẹ̀ lálásẹ́wó ṣe lè má tí ì mọ ọkùnrin? Àgbékalẹ̀ báyìí ni a bá má a pè ní irọ́ –ń –parọ́ -fúrọ́ tori pé àpèjúwe ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn ló yàtọ̀ sí irúfẹ́ ẹni tí wọn ní àwọn jẹ́. Ní ìbámu pẹ̀lú àlàyè ti a ṣe tán wọ̀nyí, o hàn gbangba pé àgbékalẹ̀ àwọn méjéèjì yapa sí òsùnwòn òótọ̀ èyí tó tako kí olùkópa parọ́ nínú ìbára-ẹni sọ̀rọ̀.

Tí a bá tún fi ojú mìíràn wò àpẹẹrẹ (8) òkè yìí níbàámú pẹ̀lú alàkalẹ̀ ofin alájọṣepọ̀ lááárín olùkópa nínú ìbára- ẹ̀nì sọ̀rọ̀, a lè sọ pé ọ̀dọ́bìnrin mọ̀-ọ́n-mọ̀ fèsí láti lè fihan ọkùnrin pé ohun tó ń sọ yé òun bẹ́ẹ̀ sì ni pé ìrírí àtí òye lórí ìṣẹ̀lẹ̀ àwújọ nípa ìṣesí àti ìhùwàsí àwọn olóṣèlú fún òun ní àǹfààní láti lè ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àgbẹ́kalẹ̀ arákùnrin náà. Ìpèdè apanilẹ́rín-ín bí irú èyí ya àwòrán bí àwọn kan tí máa ń sọ ìdàkejì ìṣe-ọwọ́ wọn látàrí ẹ̀mí ìbòra-ẹni-lásìírí tó wà lọ́kàn wọn. A tilẹ̀ máa ń gbọ́ pé lááárín àwọn olósèlú, wọn a máa dá àpárá pé; 'ẹni tí kò bá lè parọ́ láró irú wọn kì í pé lágbo òṣèlú'.

**Ìyapa sí Òṣùwọ̀n Ìṣekókó-Èrò**

Olùsọ̀rọ̀ lè tẹ̀lé tàbí yapa sí òsùnwọ̀n ìṣekókó-èró níbi tí ó bá tí ń ṣe àyàbá asán tàbí wíwá ìtumọ̀ tí kò sọnù ká. Ó tún ṣe é ṣe kí èyí ṣẹlẹ̀ níbi tí a bá ti rí àlòpọ̀ ọ̀rọ̀ onítumọ̀ pọ́nna tàbí àmúlò ọ̀rọ̀ alójú-lódì to yapa sí kókó èrò inú ìsọ.

Ẹ jẹ́ ká gbọ ìtàkurọ̀sọ̀ èyí tó wáyé lááárín nísègùn òyìnbó àti nọ́ọ̀sì ẹni tó tí ti àbẹ́rẹ́ bọ ìdí aláìsàn àmọ̀ lójiijì ló gbọ́ ìpè pé ìyanṣẹ́lódi tí bẹ̀rẹ̀:

(9) **Nurse:** Hello doctor, you mean strike has commenced and work should stop immediately'.

**Nọ́ọ̀si:** Ẹ pẹ̀lẹ́ ó dókítà, ohun tí ẹ ń sọ ni pé ìyànṣẹ́-lódì ti bẹ̀rẹ̀ àtipé kí iṣẹ́ dúró lọ́gán.




Nínú àpẹẹrẹ (9) òkè yìí, a rí bí nọ́ọ̀sì ti fi abẹ́rẹ́ sílẹ̀ sídìí aláìsàn látàrì ìròyìn tó gbọ́ pé kí gbogbo òṣìṣẹ́ dáwọ́ iṣẹ́ dúró lọ́gán. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìtumọ̀ tí ìlò gbólóhùn àṣẹ, *work should stop immediately,* 'kí ìṣẹ́ dúró lọ́gán' ní létí dókítà náà ní ó ní létí nọ́ọ̀sì tó ń gún aláìsàn lábẹ́ré lọ́wọ́ tó fí jẹ́ pé ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ kan náà ni wọ́n sì ti lò ó, síbẹ̀ àìbárámu ìtumọ̀ wáyé torí pé ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ tí nọ́ọ̀sì tí dáwọ́ iṣẹ́dúró léwu sí ìgbáyé-gbádù aláìsàn, ọ̀gangan yìí gan sì ní ó bí ẹ̀rín inú àgbékalẹ̀. Nọ́ọ̀sì tí fẹ́ ìtumọ̀ ìròyìn tí dọ́kítà fún ún lójú tó bẹ́ẹ̀ tó fi jẹ́ kí ìtumọ̀ ìpèdè náà jẹ́ alojú-lódì.

Gẹ́gẹ́ bí àwọn détà tí a yẹ̀wò lókè tí fihàn, gbogbo àwọn pọ́n-ọ́n- na tí a rí lókè yìí ló jẹ́ pé à-mọ́n-ọ́n-mọ̀ ṣẹ̀dá ni wọ́n jẹ́ yàtọ̀ sí èyí tí a kò fẹ́ kí ó ṣẹlẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú àwọn àbùdá ìmédèlò nínú ìbánisọ̀rọ̀, Púpọ̀ nínú wọn kò dédé wáyé bíkòṣe látàrí iṣẹ́ àwàdà tí a fẹ́ jẹ́ ni, ó yàtọ̀ sí èyí tí a lè yàgò fún nígbà tí a bá ń ṣàgbékalẹ̀ tí kò mú ìpanilẹ́rín-ín dání. Ní ìbámú pẹ̀lú ìpa ti ìmọ̀ ìmédèlò ń kò nínú ìlò àti iṣẹ́ tí a ń fi ọ̀rọ̀ jẹ́ nínú ìbara-ẹni –sòrọ̀, èrò mọ̀n-ọ́n-nú, ìṣekókó-èrò, òsùnwọ̀n alájọṣepọ̀ pẹ̀lú àjọṣepọ̀ ìfọ̀rọ̀dárà onípọ́n-ọ́n na jẹ́ irinṣẹ́ ìgbẹ́fẹ̀kalẹ̀ lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n- kálé nínú. Ní ìbámu pẹ̀lú àbùdá èdè èyí tomfafa hàn nínú àwọn àlàyè tí a ti ń ṣe bọ̀ nínú iṣẹ́ yìí, a gbà pé pọ́n-ọ́n-na máa ń wáyé níbi tí ọ̀rọ̀ bá ti ní ju ìtumọ̀ kan lọ tó fi ṣe dèédé pé ìsọ ọ̀rọ̀ kan fi àyè gba kí olùgbọ́ ní ju èrò kan lọ. Fún ìdí èyí, a lè rí pọ́n-ọ́n-na bí ìtónà fún ìfọ̀rọ̀ṣẹ̀fẹ̀, àmọ́ ó yẹ kí á yán-an pé kì í ṣe gbogbo ìpèdè onípọ́n-ọ́n-na ni a lè rí bí ìfọ̀rọ̀dárà nínú ìmọ̀ ìmédèlò.

## Ìgúnlẹ̀

Ní ìkádìí, iṣẹ́ yìí ti ṣàyẹ̀wò bí ẹ̀rín inú ìsọ àwàdà lórí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé ti máa ń jẹ jádè látàrí ìlò ìsọ onítumọ̀ púpọ̀ àti ìfọ̀rọ̀dárà èyí tí a gbé ka ìmọ̀ ìmédèlò. Ìwádìí yìí kò nìkan ṣàgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá ìmédèlò bi èrò mọ̀n-ọ́n-nu, etò àjọṣepọ̀, ìṣekókó èrò tí àwọn adẹ́rín-pòsónú máa ń gbé ìlò ìfọ̀rọ̀dárà onípọ́n-ọ́n-na inú iṣẹ́-ọnà wọn kà. Ó tún ṣàlàyé lórí ìsẹ́ àti ipa tí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn àbùdá ìmédèlò náà kó lórí ẹ̀rín tó máa ń jẹ jáde nínú ìpèdè apanilẹ́rín-ín.

| **Àsomọ́** | **Appendix** |
|---|---|
| *Èdè-ìperí tí a lò. Àwọn tí wọ́n gba ìràwọ̀ * lẹ́gbẹ̀ẹ́ jẹ́ àwọn tí a ṣẹ̀dá, àwọn tí kò ní ìràwọ̀ jẹ́ àwọn tí a múlò láti Èdè-Ìperí Yorùbá.* | |
| Àbùdá ìmọ̀ Ìmédélò | Pragmatic features |
| *Adẹ́rìn-ín-pòsónú | A Wit/ *A literary artist |
| *Àìbárámu/ ìtumọ̀ ajárètí | Incongruity |
| *Àkọmọ̀nà | Sticker |
| Ìyalẹ́nu | Surprise |
| *A-mọ̀n-ọ́n-mọ̀- yàgò fún | Flouting |
| *Àwórán aláàyé | Animated pictures |
| Ìlànà | Principle |
| *Ìlànà / òfin alájọṣepọ̀ | Cooperative Principle |
| Ìfini-sẹ̀fẹ̀ | satire |
| Ìfọ̀rọ̀dárà | Pun |
| *Ìfọ̀rọ̀dárà onípọ́n-ọ́n-na | Ambiguous punning |
| Ìmọ̀ Ìmédèlò | Pragmatics |
| Isọ afìmọ̀sílára hàn | Emotive speech |
| *Ìtumọ̀ àrọ́wọ́tó | Intended meaning |
| *Ìtumọ̀ ìjásí/ ìtọ́kasí | Implicature |
| Ìtumọ̀ eréfèé | Literal meaning |
| *Ìtumọ̀ ìlò | Pragmatic/ Contextual meaning |
| *Ìtúraká | Relief/Release |
| *Ìṣekókó èrò | Relevance |
| *Ìṣe-nǹkan lárọ́ọ̀tọ̀ | Superiority |
| Ìpèdè Apanilẹ́rìn-ín | Humourous speech |
| Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tọ́rọ́-fọ́n-kálé | Social media |
| *Ìlànà/ òté ìgbáfọ̀-kalẹ̀ | Maxims |
| *Òsùnwọ̀n ìgbáfọ̀-kalẹ̀ ajẹmóòótọ́ | Maxim of quality |
| *Òsùnwọ̀n ìgbáfọ̀-kalẹ̀ ajẹmọ́ọ̀ye | Maxim of quantity |
| *Òsùnwọ̀n ìgbáfọ̀-kalẹ̀ ajẹmọ́ṣekókó èrò | Maxim of relevance |
| *Òsùnwọ̀n ìgbáfọ̀-kalẹ̀ ajẹmọ́nà-ìgbàṣe nǹkan | Maxim of Manner |
| *Ìyapasí | Violation |

## Ìwé Ìtọ́kasí


Adeleke D. (2016) *Àṣà, Èrò àti Èdè nínú Iṣẹ́ - Ọnà Aláwòmọ́- Lítírésọ̀ Akinwùmí Ìṣọ̀lá.* Ìbàdàn: DB Martoy Books.

Adejumọ A. (2008) 'Satirical Elements in Akinwumi Ìṣọ̀lá's Drama. *Emerging Perspectives on Akinwùmí Ìṣọ̀lá.* Akinyemi and Falọla (ed). Trenton: Africa World Press, Inc. Pp 49-62

Akinyemi A. and Falọla T. (2008) *Emerging Perspectives on Akinwùmí Ìṣọ̀lá.* Trenton: Africa World Press, Inc.

Alaba, O. (2008). 'Akinwùmí Ìṣọ̀lá as a Humorous Writer'. *Emerging Perspectives on Akinwùmí Ìṣọ̀lá.* Akinyemi and Falọla(ed). Trenton. Africa World Press, Inc. Pp 63-72.

Alison, R. (1998) *The Language of Humor.* Routledge: London.

Apte, M.L. (1985) *Humor and Laughter:* An Anthropological Approach. Ithacal: Cornell University Press.

Àrẹ̀mú, F. (2005) *Ẹ̀rín: Òògùn Ajẹ́bíidán.* Lagos: Karohunwi Publishers.

Billing M. (2002) 'Freud and the Language of Humor' in *The Psychologist. Vol15, No.9*

Daramola, J. (1882) *Àwọn àsà àti òrìsà ilẹ̀ Yorùbá*. Ibadan: Onibon-oje Press & Book Industries.

Fákẹ́yẹ, F. (2016) 'Akinwùmí Ìṣọ̀lá Adẹ́rìn –ín- pòsónú: Àgbéyẹ̀wò Àwàdà Ajẹmọ́-ọ̀rọ̀-ìfẹ́ Nínú Fàbú'. Adeleke D. (ed) *Àṣà, Èrò àti Èdè nínú Iṣẹ́- ọnà Aláwòmọ́- Lítíréṣọ̀ Akinwùmí Ìṣọ̀lá.* Ìbàdàn: DB Martoy Books. Pp 138-151

Freud, S. (1990) Humour. A. Richards (Ed.) *Art and Literature.* Harmondsworty: The Penguin Freud Library. *Vol.14*

Grice, H.P. (1975) 'Presupposition and Conversational Implicature'. P. Cole (ed) *Radical Pragmatics.* New York: Academic Press.

Ìṣọ̀lá, A. (2008) *Akójọpọ̀ Fàbu.* Ìbàdàn: D.B. Martoy Books.

Jenson, K.E. (2009) 'Humor in Modern World. Fall. Almen: Engelsk.

Ọlateju, A. (2008) 'Stylistic Humor in the Drama of Akinwùmí Ìṣọ̀lá'. Akinyemi and Falọla (eds). *Emerging Perspectives on Akinwùmí Ìṣọ̀lá.* Trenton. Africa World Press, Inc.

Raji, S.M. (2010) Àgbéyẹ̀wò Ajẹmọ́-kókó-ọ̀rọ̀ àti Ìṣọwọ́lò Èdè Nínú Ìjálá Àlàbí Ògúndépò. M.A. Dissertation.Ọbáfémi Awólówọ̀ University, Iĺe- Ifẹ̀.

Saka, I.O. (2017) 'Ìtúpalẹ̀ Pọ́nna bi Irin-Iṣẹ́ Àmúlò Nínú *Fàbú* tí Akínwùmí Ìsọ̀lá kọ'. Raji, S., Fajenyo, S.; Aderibigbe, M (eds). Ojú Àmúwayé Yorùbá nínú Iṣẹ́ *Akínwùmí Ìṣọ̀lá.* Ibadan: Masterprint. Pp: 432-44.

Saka, I.O. (2017) 'Ète Ìpanilẹ́rìn-ín lórí Ẹ̀rọ *SósíoMidià. Ẹ̀gin:* Rájí (Olóòòtú) *Jọ́nà isẹ́ Akadá Lédè Yorùbá.* Vol.3

Sperber, D.and Wilson, D. (1995). *Relevance: Communication and Cognition.* Oxford. Blackwell.

Wilkins J. and Eiesnbram A. (2009). 'Humor Theories and the Physiological Benefits of Laughter'. *Holistic Nursing Practice.* Minnesot: St. Cloud State, University. Pp 349-354.